# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRE AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,594 FRIDAY DECEMBER 24, 1965 (2D)


## OBINRIN KAN JI EWURẸ GBE !

IBADAN:— Gbogbo enia ti O wa ninu ile ẹjọ Ijọba Ibile Ibadan lo k u n fun erin nigbati Obinrin Ọdaran kan sọ fun ile ẹjọ pe. Adahunṣe kan o sọ fun on pe, a fi bi on ba lọ ji ewurẹ gbe lọja ni on yio to oimọ laiye on.

Lẹhinti obinrin na sọ ọrọ yi tan ni o ba kunlẹ ti o nbẹ adajọ pe, ki o ṣe aanu on, ọmọ ti on fẹ bi ni o ko ba on, o ni gbogbo awọn ọrẹ, ojulumọ ati ẹbi on ni o nfi ọmọ bi on ti o si nba on ninu jẹ ni gbogbo igba.

Ẹsun ti ọlọpa to nba ọdaran ṣe ẹjọ sọ fun ile ẹjọ na pe, ọdaran obinrin ti orukọ rẹ njẹ Awulatu Adukẹ ti o ngbe adugbo Ititab, ni Ibadan ni o lọ ji ewure meji ti o je ti arabinrin Ayiatu Asakun ni ọjọ kẹsan oṣu yi.

Nigbati adajọ bere lọwọ rẹ pe kini o fun ti wi si ọrọ Ọlọpa ti o sọ sile yi ni ọdaran na ni ọmọ ni on fẹ ti ti on fi lọ ji ewurẹ meji na gẹgẹbi ọrọ Adanhunṣe ti o sọ fun on.

Adajọ ni on ko gba awawi obinrin na gbọ nitorina ki o lọ si ẹwọn oṣu mejila.

# AWỌN ỌLỌPA IJỌBA IBILẸ NBINU FI IṢẸ ṢILẸ

ABẸOKUTA:—Jẹbẹlẹ gbe ọmọ le awọn Alakoso Ijọba ibilẹ ilu Abẹokuta ati agbegbe rẹ lọwọ nigbati irohin kan wọn pe ọgọrọ awọn Ọlọpa ti Ijọba ti ẹkun Abẹokuta binu fi aye wọn silẹ pe awọn ko tun ṣiṣẹ Ọlọpa mọ.

Ninu irohin ti o de ọwọ wa lati ọwọ oniwe irohin wa lati ilu Abẹokuta fi ye wa pe ohunti o mu ki awọn Ọlọpa ti Ijọba ti Ijọba ibilẹ ẹkun Abẹokuta na fi binu fi aye wọn silẹ gẹgẹbi Ọlọpa lo ṣe alaye pe awọn ko ti mọ ohunti o fa eleyi wa.

Ṣugbọn oniwe irohin wa tun ṣe alaye ninu irohin rẹ pe ohunti o mu ki awọn Ọlọpa ti nbinu fi aye wọn silẹ ninu iṣẹ Ọlọpa le jẹmọ iṣẹlẹ nla to ṣẹlẹ si awọn Ọlọpa meje to sọnu ni abuluko kan ti nwọn npe ni Iro l'ẹba Owode ni ẹkun Abẹokuta eyiti awọn Ọlọpa ti ..ku ọkan ninu awọn ọlọpa nkan ni eti bebe Odo-Ogun ninu ọsẹ yi.

Oniwe irohin wa fi ye wa ninu irohin rẹ pe ninu ilu Abẹokuta nikan ni o ti ṣe alaye pe awọn Ọlọpa ti Ijọba ibilẹ ti nwọn binu fi ipo wọn silẹ jẹ mọkandinlogun eyiti awọn mẹta tun binu fi ipo wọn silẹ ni ẹkun Ẹgbado.

Ninu irohin lati ọwọ Oniwe irohin ni ilu Abẹokuta ni o ti ṣe alaye pe nigbati on fi ọrọ jomitoro ọrọ lọwọ Ọga agba awọn Ọlọpa ti Ijọba Ibilẹ ti ilu Abẹokuta Oloye D. A Ajagbe ni o ṣe alaye fun on pe ọna ti awọn ọlọpa ti Ijọba Ibilẹ na gba fi aye wọn silẹ fi gẹgẹbi Ọlọpa tabi pe awọn ko ṣiṣẹ Ọlọpa mọ ni o ṣe alaye pe ko le ya awọn lẹnu.

Oloye D. A Ajagbe tun ṣe alaye fun Oniwe irohin wa pe iru ohunti o ṣẹlẹ ninu ile iṣẹ Ọlọpa ti Ijọba ibilẹ yi ti ṣẹlẹ bakanna ninu ile iṣẹ ti awọn ọlọpa ti apapọ Ijọba Naijiria lasiko ti nwọn fi ko awọn ọlọpa na lọ si ile Congo eyiti o ṣe alaye pe ọpọlọpọ wọn lo binu fi aye rẹ silẹ lori alaye pe bi awọn ba lọ si Congo awọn ki yio tun padabọ wa si ilẹ Naijiria.

Nigbati Oniwe irohin wa tun bere lọwọ Oloye Ajagbe lori ohunti o ṣẹlẹ si awọn Ọlọpa ti Ijọba Ibilẹ meje ni ilu Iro lẹba Owode ni Oloye Ajagbe ti ṣe alaye fun Oniwe irohin wa pe nwọn ti ṣe eto gẹgẹbi nwọn yio ṣe fun awọn ẹbi wọn lowo lati fi ṣe iranlọwọ fun wọn eyiti o wa ninu eto olin ti awọn Ọlọpa Ijọba ibilẹ pe nwọn ni lati ma ran ẹbi Ọlọpa to ba ku si ẹnu iṣẹ rẹ lọwọ nipa iranọwọ owo.


**Overses Naps Gift**

Rochdale v's Wrexham xB
Shrewsbury vs Sc'thorpe xB
Man Utd v's West Brom xB

By LATTY-WEST



**Asalam Alaikum Jammah !**

**Nafila Oru Oṣu Ramadan.**

Lati Ọwọ ALUFA AKEWULA

ORU OJỌ KEJI 24/12/65 :— Irun mẹfa, Salamọ mẹta lori iduro Irun kọọkan, ẹo ke:-Fatiha kan; Ina-atainakalikaosara marun.

ORU OJỌ KẸTA 25/12/65 :— Irun mẹfa, Salamọ mẹta, Lori iduro irun kọkan, ẹ o ke :- Fatia kan, Ina ansalinau kan ati kul-ya-ayual Kafiruna kan.

ORU OJỌ KẸRIN 26/12/65 :—Irun mẹrin, Salamọ meji-Lori iduro Irun kọọkan, ẹo ke:-Fatia kan ati Kuliya-ayual—Kafiruna mẹta.

KA IROHIN—IMỌLẸ FUN NAFILA TI ỌLA


# Ijọba Da Adajọ Duro

IBADAN: Ninu irohin kan to de ile iṣẹ ni osan ọjọ ọ ọ 'Bọ ti iṣe ọjọ ketalelogun oṣu yi ni a gbọ pe Ijọba Ibile Iwo Orun eyiti ẹgbẹ Dẹmọ nṣe akoso ti da Adajo Kotu Ijọba ibilẹ ilu Ekiti Ọgbẹni E. S Ajibade duro gẹgẹbi Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ ilu Ekiti,

Irohin ti ari gbọ lati owọ awọn ẹgbẹ Itẹsiwaju lati Ibadan fi ye wa pe ohunti o mu ki Ijọba ti ẹgbẹ Demo nṣe akoso rẹ fi yo ọgbẹni Ajibade kuro gẹgẹbi Adajo Kotu Ijoba nipa Ọgbẹni Ajibade kuna lati jẹki ẹgbẹ Dẹmo lo on gẹgẹbi Akowe eto itan kale ẹgbẹ Dẹmo lasiko idibo si ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti nwon ṣe idibo rẹ ni ojo kokanla oṣu kẹwa Ọdun yi,

Irohin na fi ye wa pe ki nwon to se idibo si ile Igbimo Asofi Ijoba Ipinlẹ Iwọ Orun ni ijoba ẹgbẹ Demo ti da ekunwo owo—osu Ọgbeni Ajibade duro nitori pe awọn egbe Demo sope boya ni Ọgbeni Ajibade wa ninu egbe Demo mọ tabi pe ko ni igbekele ninu egbe Demo mọ.

Irohin lati ọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ itẹsiwaju UPGA tun fi ye wa pe ọpọlọpọ awọn Adajọ Kotu Ijoba ibile ni ẹkun Ekiti ni ẹgbẹ Dẹmọ ti da duro lẹnu iṣẹ wọn bakanna ni nwọn gbe awọn Adajo miran kuro ninu kotu ti o ti wa tẹlẹ tabi pe ki nwọn lọ da wọn duro fun igba die eyiti nwọn ko ni fi si lẹnu iṣẹ wọn gẹ ẹbi Adajọ Kotu Ijọba ibilẹ awọn agbegbe ti nwọn wa.

Awọn ẹgbẹ Itesiwaju tun ṣe alaye ninu irohin wọn pe ohunti awọn ẹgbẹ Dẹmọ fẹ nipe ki awọn Adajọ kotu Ijọba Ibile na wase ẹgbẹ Dẹm (NNDP) eyiti ọkọ wọn nri sinu omi bayi.

## AKIYESI

Eyi ni lati sọ fun gbogbo ẹnyin Onkawe wa ati gbogbo ẹnyin Onibara wa wipe Iwe "Irohin Imọlẹ" ko ni jade ni Ọla, nitori Ọdun Keresimesi eyiti iṣe ọjọ ibi Jesu Kristi.

Ṣugbọn ni agbara Ọlọrun o tun di ọjọ merin ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn osu yi.

A ki gbogbo nyin ẹ ku ewu ọdun, ki Ọlọrun ṣe ọdun ni abo o.

OLOTU

# KERESIMESI, ỌDUN TUN DE !

Ẹniti ọdun ba dun ba laiye oyẹ ki o ma yọ ki o si ho fun ayọ ati ki o si ma dupẹ lọwọ Ọlọrun Ọba Ogo Pataki bi a mo ti nl i kiri ode Eko ati awọn ilu nla nla ni mo ri ami pataki larin awọn ọmọ enia Ami na ni fun irọkẹjẹ fun tita orisirisi awọn nkan ti awọn yio fi ṣe ọdun yi Mo bi gbogbo iru awọn ẹni bẹ yẹ mo si ngbadura pe ki Oluwa pa le gbogbo nwọn o, Pataki julọ kini idi ti gbogbo aiye nyọ fun Ibi Jesu? Kini ere ọjọ Ibi Jesu yi?

Kini si ni itumọ Ibi Jesu yi fun gbogbo awọn ti nyọ y? Jẹ ki nsọ die si awọn ibere wọyi idi ti Olutele Jesu ni pe a bi Jesu fun ilaja larin awa ati Ọlọrun A bi Jesu ki o le gba wa ninu ẹṣẹ wa.

A bi Jesu ki a ba le jogun Ijọba Ọlọrun pẹlu rẹ Awa ti ṣẹ a si di abuku si ogo Ọlọrun Ki a ba le ni Ajogun pọ pẹlu Ọlọrun a bi Jesu fun gbogbo wa fun idande kuro ninu ẹṣẹ wa gbogbo lẹhin ti a ba gbagbọ

O ye ki gbogbo wa ma yọ pẹlu nitori ọrọ Ọlọrun sọ fun wa pe ọpọ ogun Ọrun yọ si Ibi Jesu pe' Ogo ni fun Ọlọrun loke Ọrun ifẹ inu rere si enia gbogbo.

Ti awọn Angeli ọrun ba yọ si ibi Jesu ese ti awa na ko ni lati yọ? Nitori ibi Jesu jẹ imi ay fun gbogbo awọn to wanimu irora o an Ise Woli Isiha so pe "Nitori abi olugbala fun wa tabi nitori a bi mo kan fun wa' a fi omokunrin kan fun wa; Ijọba yio si wa li ejika rẹ si o si ma pe oruko rẹ ni Iyanu, Oludamoran Olorun Alagbara Baba Aiyeraye, Omo-Alade Alafia.

Ijọba yio si bi ,alafia ki yo ni ipẹkun, lori Itẹ Dafid ati lori Ijọba rẹ lati mato o ati lati fi idi rẹ mulẹ, nipa idajọ ati ododo lati isisiyi lọ ani titi lai. Issiah ori 9 ẹṣẹ 6 ati 7

Eotitọ ati lododo ko si enia kan ti ati sọ iru asọtelẹ bayi fun lati igbati aiye ti ṣẹ. Nitori na ibi Jesu jẹ ihhanni ni pe Ọmọ Al dẹ alafia ni iṣe Ati pe Olugbala araiye ni Jesu

Mo tun bere lọwọ ẹnia onkawe yi pe kini Ibi Jesu jẹ fun yin? Ibi Jesu to jẹ ifẹ inu rere si enia fi bẹ ẹ pe ngbati iwọ ba nje ti o si nmu tauti awọn te wa yi ẹ ka ti awọn ko ni bi iwọ ti ṣe ni. Wo yika awọn ọmọ lainí baba ti o wa ni tosi rẹ

Ibi Jesu nsọ fun ọ kẹlẹ kẹlẹ pe o nilati ranti iru awọn ẹni bẹbẹ lọ Ibi Jesu ẹ i dọde ẹran ninu igbo n da u reo i yapi uro lọna ti Ọlọrun fi lelẹ fun ọ lati ṣe

Ife i u rere si enia ni Ibi Jesu je fun gbogbo wa. Mo ni Ibi Jesu ti o jẹ itura ki o m si mu itura wa ba gbogbo awọn to wa ainu inira nipa ti aiye yi.

Ki gbogby awọn to wa ninu oku kun aiye yi ma sai wa sinu imọlẹ ti Jesu na. Gbẹ ọrọ ire ti Ọlọrun sọ fun wa

Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ gẹ ti o fi omo Bibi ine Rẹ nikansoso fun ni pe nikẹni ti o ba gb gbo yio ni iye ainipẹkun J h 6:16

Ki Ibi Jesu masai pese iṣe rere fun gbogbo awọn ti ko ri iṣẹ ṣe ninu odun ti o kọja. Ki Ibi Jeṣu marai jẹ dide fun gbogbo awon alaisan gbogbo po o. Ibi Jesu sọ fun pe gbe ori rẹ soke iwo alarẹ nitori ayo mbo lowuro,

Daju Ibi Jesu yio se eyi na fun gbogbo ẹni ti ewuro aiye wa ni sakani wọn Amimi.

Lati Ọwọ



S. O. Jaiye

ki ṣe fun imuti para ki a ma yira ninu eebi, Ti iwọ ba ṣe iru nkan bẹ mọ da ju pe o ma oruko ẹgan ba Oluwa rẹ.

Nigbati iwọ ba nro ibi Ikan rẹ si ẹlomiran mọ da ju pe o mu oruko ẹgan ba Jesu Oluwa rẹ. Nigbati o ba nde dẹ ọmọn'keji rẹ bl

Ninu Iwe ikini Ibi Jesu yi mo ki gbogbo ẹyin okawe yi pe ki Ọlọrun se ọdun yi ni o un abo fu gbogbo wa ki Ọdun 1966 jẹ ọdun iyipada si rere fun wa

Ki awọn agan masai fi ọwọ bọ oṣun ninu ọdun yi o ki ilẹ wa tise Naijiria ma sai mu ọpọ eso rere wa ba gbogbo wa E ku ọdun ẹ si ku iyedun alemọ ni porogun ni ọmọ bẹ ni ki o ri fun gbogbo wa o.

O digba diẹ

---

# YẸYẸNATU

## ONIYẸYẸ EKO

Olotu:- Yẹyẹnutu, o ku ipalẹmọ ọdun

Yẹyẹnatu;- Yes sir, a npa a mọ,

Olotu:- Ki Ọlọrun ṣe ọdun ni abo.

Yẹyẹnatu:- Lẹhin ti ẹ ba ti ṣe e ni akọ

Olotu: Bawo ?

Yẹyẹnatu: Iyẹn ni pe ẹ kọ gbọ ti awọn oniṣowo nsọkun kiri

Olotu: Pe kini ?

Yẹyẹnatu; Nwọn ni gbogbo bisko ti awọn ra wọn ko ta

Olotu: Kini de ?

Yẹyẹnatu: Nwọn ni nitoripe awọn Ọlọpa panapana nṣiṣẹ pupọ nitisiyi

Olotu: Ṣebi o tilẹ sọ wipe Subẹru fẹ ṣe iṣẹ panapana ni tjẹelo ?

Yẹyẹnatu: Lootọ ni, ṣugbọn ọjọ yẹ ti pẹ

Olotu:- Nisisiyi nkọ ko fẹ ṣe mọ ni.

Yẹyẹnatu:- O ni iṣẹ wọn ti pọ ju bisisiyi awọn ti Eko ode Ijẹbu ṣiṣẹ nisisiyi boya

Olotu:- Ibikibi ti ina ba ti njo na ni panapana gbọdọ ṣiṣẹ

Yẹyẹnatu:— Ha ! olotu ẹ tun de pẹlu irọ ko si baba panapana ti o le de gbogbo ibiti ina ba ti jo

Olotu:- O dara daruko ibi kan

Yẹyẹnatu:- Nigbati ina njo Ioko wa ni Ifọ kini ṣe ti panapana ko yọju ?

Olotu:- Ṣebi ẹ fẹ da oko ni, iyẹn yatọ

Yẹyẹnatu:- O dara nigbati ẹni ti nwọn ni o jona ni Ijẹbu njo nibo ni panapana wa ?

Olotu: Ṣe inu tirẹ wa ndun si gbogbo kini wọnyi ni ?

Yẹyẹnatu: Inu mi ṣe le dun, Inu mi ko dun kẹ Inu ndun mi ni

Olotu: Kini ndun rẹ ninu ?

Yẹyẹnatu: Olotu Akintola ti sọ pe ko si ibiti alafia wa to West Mo mọ pe olootọ ni. Nigbati mo ka a ninu iroyin ni ijeo o inu mi dun mo rẹrin titi inu ndun mi.

Olotu; O jẹ ẹọra rẹ.

Yẹyẹnatu: Ṣe ẹnyin ko fẹ alafia ni emi fẹ ni temi o.

Olotu: Adura alafia na ni a ngba

Yẹyẹnatu: Alafialia bi alafia ti Lajia kọ ṣa o.

Olotu: Oniṣokuso. sa kuro fun mi.

---

## Angeina Super — Rose

(O TI LỌ WA JU)

Eleyi ṣẹṣẹ jade ni ko si nita rara Aṣẹṣẹ jade akan ako mọ ibiti o nlọ Ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju" Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lọmọde lagba ọkunrin ati lobinrin O tun wa fun irun didi ati kiko elo- e o nm i iru okunrin pa p ma dan ki o si iọlo O ma n ara ni ẹwa ak tun wọ ara yio si yọ jade pere pere. Bi enia duda ba loo yio ma d gẹgẹbi jigi Enia pupa kuku ti wa tẹlẹ.

Oere sire wa ibi ki o kowe fun tire loni ki o to t n n lest African Cosmetic Industries" 35' Ọmọwunmi S Tao District Council Mush o ẹtọju ara ati irun nyin ẹt

Wen p ku ni 1/3d fun ẹyọ kan 15/- fun mejila

## Itan Igbesi Aiye Mohammad Ali-Jinnah

# ENITI O DA ORILE-EDE KAN SILE

Ni dede agogo mewa kutukutu owuro ana o'o ojo Bo ti Ise ojo kelalelogun osu yi ni Ir h n k n de si ile ise wa ati ile ise Asoju Ijoba orile ede ile Pa istan ni Na ri ni nomb 26, C tholic M ssion St eet Eko wipe ni ol t ise oj ked gbon osu yi n Olula O'ogbe Alhaji Moh mmad Ali Jinnah yio pe omo dun metadinlogorin ninu aiye

Irohin na tun se alaya siwaju wipe inu od in 1878 ni won bi Alhaji M h mmad Ali Jinnah sinu aiye ni ojo kedogbon osu kejila odun 1878 ni Karauchi.

Ogbe i H A Chisti eni ti ise akowe eto Irohin fun ile ise Asoju Ijoba orile ede le Pakistan ni Naijiria so fun onkwe Irohin wa ni iore ose y. wipe ia i bi ojo merin sehin wa nis siyi ni awon enia orile ede ile Pakistan ti bere ma mura s le lat se ajoyo ayajo iranti ojo ibi Alhaji Ali Jinnah ninu i u awon.

Alhaji Ali-Jinnah yi je okan ninu awon enia ti won ja fun Ominira orile ede ile Pakistan ni gba a ye re ai o to di wipe o ku.

Alhaji Ali Jinnah yi je okan ninu awo omo orile ede ile Pakistan ti o je ojo-g-ọn enia ungbati o ti di ọmọ ọdun marun ni awon ob r t ran lo si ile iwe.

Nigbati yio si fi di omo ogun odun, o ti para eko re ni inu ile eko Onifasiti Ibadan, o si se daadaa ninu idanwo ise Agbejoro ti awon se ninu odun na.

Bi o ti pari eko re na ta ni o ti pada wa si ile, ti o nso ise Agbejoro re ninu ilu Bombay ati ati ni Karachi.

Fun odun odun meta gbako ni Alhaji Ali-Jinnah n nse ise amofin re ninu ilu won, ungbogbo awon enia si bere m se pe si ise ti awon ba ti se le se!

Sugbon lati yalo u gbogbo awon ara ilu Pakistan gbogbo awon amofin ti nwon ti wa ninu ilu na siwaju Ali Jinnah, ni o nse dada ju won lo ti o fi je wipe ni gbogbo asiko na, Ali-Jinnah ni awon enia ngbo ise l n ungbayowu ti awon ara ilu ba ti ni ejo kan lati se.

Sugbon nigbati yio fi to b ọdun mẹrin si asiko yi, Al-Jinnah ti di olokiki enia yiau gbogbo aiye ti nwon si gbo nipa ise ka ibi gbogbo ti o n je wipe, nitori awon enia yio ba se ni u ilu Pakistan ni gbana, bi nwon ko ba u ri Ali Jinnah, ohun ni ko ti ti ni dara to ni oju won.

Sugbon nigbati o di inu odun 1896, ni Ali Jinnah



**Mohammad Ali-Jinnah**

ba beresi ma a se Is Oselu kun ise re ti o nse' o e okan ninu awon t' won lo si ilu Oyinbo ti nwon so wipe awon yio gba Ominira fun ile India

Fun opolopo igba ni awon enia ti yan an gegebi Asiwaju egbe won ninu awon Ijo Musulumi ti won wa ninu ilu na nigbati won ri wipe o wulo pupo fun won ninu ohun gbogbo.

Nipa siso na wonyi gbogbo awon Musulumi ti nwon da onruru egbe sil ninu ilu na ni Ali-Jinnah ba so'ro ti awon enia na pupo si ona kansoso.

Eyiti nwon ti ma nso tele wipe, awon kan nje "Hi dus - Muslim, ati awon kan Muslim League, nigbati Ali-Jinnah de gbo gbo won ni o apo ti won si di okansoso ti ko si iyato kankan larin awon enia na mo.

Nigbayi ni awon enia na to mo wipe, okan na ni gbogbo awon ti awon ti nba ara awon ja ti awon si nso wipe awon kan yato si awon ni ona isin tabi awon Musulumi kan lo po ju awon kan lo. A si fi ye gbogbo won o si tun mo d won loju Ipe, Olorun kanna na gbogbo agaegbe awon nsin.

Sugbon bi Ali Jinnah ti nse y o da mo p lo p w n enia na ninu, nwon s nwa ona l ti baa ja ninu gbogbo ohun ni o se K si t n pe pupo eh n e'ewi ni nwon ba da rogo dyan kan sl larin awon omo egbe Musulumi inu ilu a, ti awon kan si so wipe, awon yio ba wa a bi ko ba le fi awon sile gegebi o ti e ba n - on.

Nit ri ro i ni Ali Jinnah ba kuro ni ilu o si lo si ilu Oyinbo, nibiti o gbe fun opolopo odun ki o to tun pada wa si inu ilu Pakistan.

Sugbon nigbati o pada de awon enia fe n e pupo ju ti tohin wa lo awon enia si gb gb gbo hu t ti so fun on lati ohun wa ipe ohun rere i

Nigb ti o bere ise r ti e di odun kan ati os k n ni awon enia or le ede Pakistan gb Ominira ni abe Alhaji Ali Jinnah ti awon enia na si yan g eb Asiw ju won n'n odun na

L ti Igb na n awon enia Orile ede i e Pakistan ti bere si ma ya ojo kedogbon su ejila odun t ise ojo ibi Ali J nah si oto, ti nw n s nfi jo na se ariy fun i n gba aiye re titi ti o fi ku

Lati Igbati o si ti ku na ni awon enia ati Ijoba Orile ede Pakistan t ya ojo na si oto, t nwon si i nse iranti re gbogbo awon osise ni nw n yio gb Isinmi ni ola lati i se ira t ojo ibi Ali Jinnah.


**WANTED**

Advance Apprentice and Apprentice Printers.

Apply In Person

Irohin Imole's Office

16, Bamgbose Street LAGOS

# Awọn Ọmọ ilobu Kọ Ile Iṣere

ILOBU:— Awọn ọmọ Ilobu to wa ni ilu Eko da egbe kan silẹ ti awọn ọmọ egbe to wa nibẹ je ogbọn ni nwọn ti ṣe ipade nla k u t' gbogbo wọn si fi ọro wọn ṣọkan lati k si nu Il u lati lọ kọ ile ere kan si ilu wọn ni toripe ti nwon ba lọ sile nwon k si aye to gba ogunlọ enia lati ṣe ipade

Ni opin ọsẹ ti o koja ni awọn omo egbẹ yi lọ si ilu Ilobu lẹba ilu Oshogbo la lọ berẹ eto ti nwọn ti gba ninu ilu Eko nwọn si mura gidigidi lati ri wipe nwon ṣe iṣẹ na ni aṣeyọri awọn ti d owo lati fi ra pako, paanu, eso ati wọn nkan elo ti nwọn yio lo fun ile na

Irohin lati ilu Ilobu lẹba Oshogbo ṣe afikun pe awọn omo ilu na ti o wa ni ile ẹkọ giga ti mura silẹ lati ṣowọpọ mọ wọn ki iṣẹ na le ba tete pari ni asiko paapa ki ọdun tuntun to

ka ọsẹ nilẹ ati wipe ki awọn ọmọ ile ẹkọ to berẹ si pada si ile ẹkọ nwọn

Ati eto ti nwọn ṣe ni wipe ko ni gba awọn ju ọsẹ meji lọ ti awọn yio fi pari kikọ ile na de opin, a tun gbọ pe awọn ọdọ ti o jẹ enişẹ ọwọ bi ṛelẹrẹle kanlekunle rẹle d'ọtun gbẹna gbẹna ti o wa ni ilu Ilobu ti mura silẹ lati dara pọ mọ wọn lai ni gba owo rara.

A gbọ wipe awọn ọmọ Ilobu ṣe ayeye kini ku abọ ni ọjọ ọjọ Bo tiṣe ọjọ keta lelogun osu yi

* * *

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Mura gidigidi lori nitoripe enre ati igoega wa fun ọ lọnu iṣẹ alagba kan yio s ṣe iran ọwọ fun ọ

PISCES (Feb 21 Mar 20) Irẹ wẹsi yio wa fun o loni o si yẹ ki o bon ki o si toju alafia ara rẹ

ARIES (Mar 21-April 20) Ṣe akiyesi gbogbo ohun ti iwo yio ma lonı, bi ọt tabi o ni ki o ma ba jẹ ahara mọ oi jẹ

TAURUS (April 21 May 20) Bi o ba ri pe iwọ ko le ṣe ki o maṣe mu ọti loniibi o ti wu ki o kere to maṣe fi ọwọ kan mọ to si wiwa nitori ewu mbẹ

GEMINI (May 22 June 21) Pe Ato ati Ọdọna inu re ki o si ṣe ikilọ fun wipe ọu rẹ ko gbọdọ kan ọti lile lati mu loni

CANCER (June 22 July 22) Ina arisiki rẹ fẹ lat ma jo, ṣugọọ anfera fẹ ba a ọ tun ọ, ṣe suru ki o si lọ ra ma kọ Iwe ti o fẹ o

LEO (July 23 Aug 22) Ayọ yio gọ fun ọ loni, gbo gbo ohun ti iwo ko ti le ṣe ni iwọ yio ma ṣe ki o si pe se owo ina sile fun ara rẹ lati lo

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ọjọ oni ko ni gbamuṣe obẹ fun ọ, ṣugọọ ki o maṣe fi ara silẹ fun aisan aisan, gbogbo enia ni yio ma ki ku ọdun ku iyedun nwon o si nilẹ lati ran ọ lọwọ

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Mura lati oni lọ, ki o si bẹ ọsi ṣe gbogbo awọn ohun ti o ti gbin si okan, awon enia yio e u i w dapọ tu ukan na yio fi d ra

SCORPIO (Oct 24 Nov 23) Ọrọ nowọ pamọ ri ọ fẹ si yi iṣrun bi o oa si ri, iri aju eyi dara pọlu, o yẹ ki o pa ju io iṣ to ti o nde si o yi.

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Ṣọra pupọ gidigidi fun ohun kohun ti tise ti iji, Bi n ọọ gba iẹti ọrun nṣe ni ki o y ti osi si Suru ni baba iwa.

SAGITTARIUS (N v 22 Dec 21) Ohun kohun ti nwọn ba tọ lọwọ rẹ, loni, maṣe ṣe ahun pe ko s, ayọ fi ohun ti iwọ ko ni.


## Ha Kini Eleyi O




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils d ra pupọ An O dara iu gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun re si da ra pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu yara na ay n ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si d w, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo ya muyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọ ọmọ rẹ y o si sun d radara

Ki o ri d ju pe ogun yanmu anmu o' ri erin m ẹtay nwọn mu un o

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa n ṣọbu eitaja kakiri orile ede yi

DISTRIBUTORS

AMOS GBENLE & BROTHERS

34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

* * *

BERE FUN OJULOWO ADI_ELEGBO

# "Congreve's Iodo Form--Ointment'



Atmatase ni egbọ́g" ADI-ELEGBO" yi i fun itọju gbo gbo oriṣiriṣi "EGBO—ESẸ" ni kakia bi o ti wun ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awọ ko idọti ni bi ẹr gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara. Lẹhinna oju egbo ṣo ba ji si u yio je l oju re ru wa sile, y o si pọn daradara run rakiru ko si mọ ae ewere ni yio si san patapata Alafia de si ọ niyen:

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si sale ise yi ni igbe ranse lọ ra Bibẹko awon Eleru abi onijibiti ylo ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba e ra o

Bere eg bọg yi ni ṣobu awọn :—o

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

# Eniti O Jẹ Ewe Taba Igbo F'ẹwọn Ju'ra

ỌWỌ:- Gbogbo enia ti o wa ninu ile ẹjọ Ijọba kekere ti ilu Ọwọ ni o ko sile fun erin nigbati Olopa ti o mba ọdaran kan ṣe ẹjọ sọ fun ile ẹjọ pe, bi awọn ti fẹ ka taba igbo mọ Ọdaran na lọwọ ni o ba ju si ẹnu ti o si ejẹ bi ẹni jẹ obi gbanja ni ọjọ na.

Olopa ti o lọ mu Odaran na Ogbẹni Dominic Obi sọ fun adajọ Ogbẹni O. O. Sawyer pe, nigbati nwọn gbọ pe odaran na jale ni ọna awọn ba ni ki awọn meji lọ yẹn ile odaran na wo.

Ogbẹni Imoral, ti o jẹ Olopa tun sọ fun ile ẹjọ na pe, bi awon ti nlu ile Ogbẹni Obi ni awọn bari taba igbo ti nwọn ti we si ọna meje ninu ile re ṣugbọn ki awọn to mu taba sayi, ọdaran na ti ki mọ awọn lọwọ ti o si da si ẹnu ti o bẹrẹsi run lẹnu ti o nje bi obi gba ja.

Ẹṣẹ ti Ogbẹni Dominic Obi ṣe ki nwon to lo tu ile rẹ ni wipe o ba awon kan ja lori ebi ṣugbọn taba igbo ti nwon ba ni lẹ rẹ yi wa tun buru jẹ'.

Ninu idajo adajo Ogbẹni O. O. Sawyer ni o ti ni ki odaran na lo si ẹwon oṣu mẹsan.

Ninu ile ẹjọ kanna ni adajọ ti da Ogbẹni Bose le Abu lare lori ẹsun pe o fẹ ba alafia arin ilu jẹ Ogbẹni Abu hu iwa na ni adugbo kan ti o nje Eh n ogbe ni ilu Ọwọ ni ojo keje osu Kọkanla ninu ọdun yi.

---

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYAMRIN** TỌNIK

ALE-BI-ALE Egbogi Tọiki jamọnu, tiiun ti gbogbo ura Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ dajudaju fun Agbara ati Ajẹbidan iṣẹ l ra agbalagba Ọkunrin ati Obinrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun dada de ọkan l san tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ṣefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kaulẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti koja ọgbọn ọdun si adọri tabi ubẹ lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di ọtun pafapata inu rẹ a jẹlọ ẹran ara rẹ ti o g banjọ yio bi yabo dada ti Ara rẹ yio gbe kankan ni ugba yio sao pẹlu ioq m adeu brode o iyẹn d b ṣ



Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Street Lagos P O Box 333

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

ATI NI ŞOBU
IŞE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN

# Kere o Kere o! Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanun Egbogi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na njẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi po ilera fun gbogbo awọn ti amudi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbẹ nṣẹ deede, inudrun ngbọkugba ara wiwo, Ẹsẹ ri ẹhin didun sisan ati aiko riran kedere ko duro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki ejak ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe enia nipa sise di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile meje abọ (7/-6 pere Igo kekere şile mẹrin abo (4/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Şọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORES
8 Palm Church Street. Phone 22757
LAGOS Nigeria, (Ọja Ita Faji

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

---

IWE KOṢEMANI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO

NINU ODU MERINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da se AYẸWO fun ara rẹ

"KOSEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE

8, Idumagbo Avenue
Lagos, Nigeria (Leti Ọja Jankara)

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,594 FRIDAY DECEMBER 24, 1965 (2D)


## INA NLA KAN JO NI ẸGBADO

ẸGBADO:—Ninu irohin to de ile işẹ wa lati ọwọ Oniwe irohin wa ni ekun Ẹgbado ni o ti şe alaye pe gbogbo apapọ ile ti o jona ni ẹkun Ẹgbado si je mẹrinlelogun eyiti o jẹ wipe ninu ọsẹ yi ni awọn enia kan ti Ọlọpa ko ri mu lọ dana sun ile awọn Olori ẹgbẹ Oşelu to wa ni awọn ilu.

Irohin na tun fi ye wa pe ninu awọn ilu ti awọn enia na ti dana sun awọn ile wa ni Ado-Igbessa eyiti awọn enia na dana sun ile mefa ati ile mejidilogun ni Idi—Ayin ati Gbada ni ẹkun Ẹgbado.

Oniwe irohin wa tun şe alaye pe awọn Ọlọpa ti nwọn ko lọ si awọn ilu ti nwọn ti dana sun awọn ile na ni o si je pe awọn enia na yio kọkọ fi epo moto si ara awọn ile na yika ki nwọn şa ibana si ile na.

Bakanna ni awọn Ọlọpa ti wọn ko lọ si awọn agbegbe ti nwọn ti dana sun awọn ile na tun şe ikede pe awọn ti ri enia mẹrinla mu lori işẹlẹ to şẹlẹ si ile na atipe awọn tabi ohunti nwọn mọ nipa ile ti nwọn dana sun na.

Irohin tun fi ye wa pe awọn enia kan tun yinbọn si Oloye Asiru Borokini ti işe minista kekere ni ile işẹ Minista Alamojuto eto irohin fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun tẹlẹ ati ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ fun iha Gusu Ẹgbado ninu ibo to kọja lọ yi.

# ADAJỌ KOTU KAN FI ẸGBẸ DẸMỌ SILẸ

MUSHIN:- Lati bi nkan oşu meji sehin ni irohin to ti nde si ile işẹ wa lojojumọ lori awọn Adajọ kọtu ijoba ibilẹ, ati awọn Amugbalẹgbẹ ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti nwọn binu fi aye ati ẹgbẹ Dẹmọ silẹ pada sinu ẹgbẹ itẹsiwaju UPGA lori eto ab·yọri idibo si ile igbimo Aşofin Ijoba Ipinlẹ Iwọ Orun to koja lo yi.

Ninu irohin to de ile işẹ wa ni kutukutu owurọ ọjọ ọiọbọ ti işe ọjọ kẹtalelogun oşu yi ni a ti gbọ pe ọkan ninu awọn Adajọ kọtu Ijọba ibilẹ to wa ni Muşhin Alhaji M.L. Akinwumi binu fi ipo rẹ silẹ gẹgẹbi Adajọ kọtu Ijọba ibilẹ onipo kẹta.



OLOYE AKINTỌLA
Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe Alhaji Akinwumi tun binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) eyiti Alhaji na şe alaye pe on kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ lori ero ọkan on ati awọn enia on ti on lati gbọ ọrọ si lẹnu,

Ninu iwe Alhaji Akinwumi ko si Alaga eto ijoba ibilẹ fun ijọba ipinlẹ Iwọ Orun ni o ti şe alaye pe on fi ipo on silẹ gẹgẹbi Adepo kọtu ijọba ibilẹ onipo kẹta ti ilu Mushin Şugbọn ibọn ti awọn na yin si Oloye Borokini ko si ba eyiti o jẹ wipe ni ọjọ Işẹgun ti işe ọjọ kọkanlelogun oşu yi ni awọn enia na gbiyanju lati yinbọn pa Oloye na ni ọna Ado Igbessa.

Bakanna ni awọn Ọlọpa mẹta ti nwọn ba Oloye Asiru Borokini lọ si Ilu Ado - Igbessa lati lo da abo bo tun yege laifi ara gbọgbẹ ibọn ti awọn enia na yin si wọn.

Irohin awọn Ọlọpa ti ilu Ilaro ti ye wa pe Oloye Asiru Borokini lọ si ilu Ado - Igbessa lati lọ ki awọn enia rẹ to wa ni ilu na eyiti to jẹ pe ki Oloye Borokini to pada de lati ilu na ni awọn enia na ti lọ fi nkan di oju ọna lati maşe jẹki Oloye Borokini ri ọna gba koja pẹlu awọn enia rẹ şugbọn bi awọn enia na ti nko awọn nkan ti awọn enia na si di oju ọna kuro ni nwọn bẹrẹsi gbọ iro ibọn lọtun ati losi lati lọ gbo.

Awọn Ọlọpa na pẹlu Oloye Borokini si sa asala fun ẹmi wọn eyiti nwọn fi ọrọ na lọ sun awọn Ọlọpa to wa ni Idi - Iroko ati ni ilu Ilarọ lori ohunti o şẹlẹ si wọn.

Awọn Ọlọpa ko ri enia kankan mu lori ohunti o şẹlẹ si awọn enia na titi di asiko ti a fi nkọ irohin yi.

# Onişowo Kan Gba Idajọ Ewọn, O Bu Si Ẹkun

MINNA:— Ọrọ ko wọ ni ọjọ ọbọ'Bọ si işẹ ọjọ kẹtalelogun osu yi nigbati Adajọ agba ti kọtu kekere ti Ilu Minna Ipinlẹ Ariwa Ile Naijiria ni ki onişowo kan Joseph Oguntana lọ fi ẹwọn odun meji jura eyiti ọkunrin ọdaran na si bu sẹkun lori ẹsun pe ọkunrin onişowo na lọ na ọwọ ayederu korẹnsi ti o jẹ pọun marun alapapọ.

Ninu oro Ọlọpa to ba ọdaran okunrin onişowo na şe ẹjọ ni o ti şe alaye fun ile ẹjọ na pe ninu oşu kerin ọdun yi ni Joseph Ogunlana lọ na korensi alapapo ponun marun (£5) lati lo fi ra oja eyiti owo na si jẹ owo ayederu ti ki işe ti ijoba ati pe iru nkan bẹsi lo di si ofin ilẹ Naijiria

Ninu Idajo Adajọ agba kotu kekere na ni o ti şe alaye fun Ọkunrin odaran onişowo na pe, Njẹ o ni oro kankan lati so lori ẹsun ti Ọlọpa ka si lẹsẹ yi okunrin na si se alaye fun Adajo agba na lati ua rijọ on ati pe on ko si mo pe owo na ko dara.

Lesekese ti Adajo na şe idajo ti o si ni ki odaran na yara lo fi ẹwọn odun meta jura ni o ba bu se kun pe ki Adajọ dari jin on.

**Ẹ maa ka Iwe Irohin Imọlẹ Ki ẹ si maa Polowo Ọja yin sinu rẹ Loojumọ**


Printed & Published By Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 2p/12/65